# Ète Ìṣàkíyèsí Alátẹnumọ́ nínú Ẹ̀ka-Èdè Ọ̀wọ̀

*Eleshin-Ajikobi, Alimot F.*


## Àṣamọ̀

*Ète ìṣàkíyèsí alátẹnumọ́ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ọ̀nà tí à ń gbà ṣe ìdàrọ èdè káárí-ayé lábẹ́ gírámà onídàrọ olófin ìyídà. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni a lè gbà gbé ète yìí yọ, èyí sì wà lọ́wọ́ èdè tí a ṣàmúlò ní pàtó. Àwọn èdè kan máa ń ní atọ́ka tí ó ǹ ṣiṣẹ́ àkíyèsí alátẹnumọ́ àwọn mìíràn kì í ní. Ààyè tí atọ́ka yìí ti máa ń jẹyọ nínú àwọn èdè tí wọ́n ní pàápàá tún yàtọ̀ síra. Bí atọ́ka yìí ṣe ń tẹ̀lé fọ́nrán tí a ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún pẹ́kípẹ́kí nínú èdè kan, ni ó ń jìnnà kétékété sí fọ́nrán náà nínú èdè mìíràn. Èròngbà iṣẹ́ yìí ni láti ṣe àfihan ọ̀nà tí à ń gbà ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ tí ó jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀ka-èdè Yorùbá. Tíọ́rì Oníwọ̀nba Èròjà ni a gbé iṣẹ́ náà lé. Détà tí a lò fún iṣẹ́ yìí jẹ́ àbájáde ìwádìí wa lórí ẹ̀ka-èdè náà, èyí tí a rí gbà lẹ́nu àwọn elédè ọ̀hún ní ìlú Ọ̀wọ̀. Iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé kékeré kọ́ ni pàtàkì ìlò ìró ohùn nínú èdè Yorùbá, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn pé àmi ohùn ni ó ń ṣiṣẹ́ atọ́ka àkíyèsí alátẹnumọ́ nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀.*


*Kókó ọ̀rọ̀:* *àkíyèsí alátẹnumọ́, ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀, ìró ohùn, tíọ́rì oníwọ̀nba èròjà*

## Ìfáárà

Èdè Yorùbá jẹ́ ọ̀kan lára èdè tí ó gbajúgbajà tí à ń sọ ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Apá iwọ̀-oòrùn gúsù orílẹ̀-èdè Nàìjíríà (southwest) ni àwọn olùsọ rẹ̀ fi ìkàlẹ̀ sí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n tàn káàkiri orílẹ̀-èdè náà. Bákan náà a rí àwọn olùsọ èdè náà ní àwọn ìlú bi; Cotonou, Togo, Brazil, Sierra Leone, Cuba, apá kan ní ilẹ̀ Amẹ́ríkà abbl. Èdè yìí gbòòrò débi pé ó ní oríṣiríṣi ẹ̀ka èyí tí Ọ̀wọ̀ tí iṣẹ́ yìí dá lé jẹ́ ọ̀kan nínú wọn. Ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn onímọ̀ ṣe pín in, jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀ka-èdè Yorùbá tí à ń sọ ní apá gúsù ilà-oòrùn Yorùbá (SEY). Ìpínlẹ̀ Oǹdó ni a ti ń sọ ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ ní àwọn agbègbè bi; Ọ̀wọ̀, Emùré-Ilé, Èchò, Àjọwá, Epòró-Ilé, Ìpelè, Ifọ́n, Uté, Ìpẹ̀nmẹ̀ abbl (Ẹlẹ́shin, 2019:18).

Àhunpọ̀ àṣàyàn ẹyọ-ọ̀rọ̀ tí ó tọ́ nípasẹ̀ òfin ìyanra láti inú àká-ọ̀rọ̀ ni a fi ń ṣe àgbékalẹ̀ èrò ẹ̀ni ní ìlànà gbólóhùn. Gbólóhùn yìí sì ni a fi ń ṣe àgbéjáde èrò ẹni nínú èdè yòówù kí ó jẹ́ lágbàáyé. Gẹ́gẹ́ bí Chomsky (1986) ṣe sọ, ó ṣeéṣe kí ìyídà wáyé lórí ìhun tí elédè ní lódò ikùn rẹ̀ (ìhun ìpìlẹ̀) àti ìhun tí ó fọ̀ jáde (ìhun òkè) látàrí ipa òfin ìyídà. Ìpa òfin ìyídà yìí máa ń ṣiṣẹ́ lórí ìhun gbólóhùn lágbede méjì ìhun ìpìlẹ̀ àti òkè. Ó sì máa ń so ìhun ìpìlẹ̀ mọ́ ìhun òkè nítorí pé ìbáṣepọ̀ gbọdọ̀ wà láàárín méjèèjì bí ó ti wù kí ìyídà wáyé. Radford (1988) náà tan ìmọ́lẹ̀ sí ìyídà. Ó jẹ́ kí ó yé wa pé, ìyídà ni ọ̀nà tí ìhun ìpìlẹ̀ gbólóhùn àti ìhun òkè gbà ní ìbáṣepọ̀ látárí ìlò àwọn òfin tó ń ṣe ìgbéfò. Ó wí pé, ó ṣeéṣe láti yí ọ̀rọ̀ ẹnu ọlọ́rọ̀ (active sentence) sí ọ̀rọ̀ àgbàsọ (passive sentence) bí ó ti ṣeéṣe láti yí gbólóhùn àlàyé sí

gbólóhùn ìbéèrè nípasẹ̀ ṣíṣe ìyídà. Lamidi (2008) náà fi yé wa pé, ọ̀nà mẹ́rin ni ìyídà lè gbà wáyé nínú ìhun gbólóhùn. Àwọn sì ni; ìpajẹ, ìfirọ́pò, ìfibọ̀ àti ìgbéfò. Àwọn ìyídà tí ó lè dé bá ìhun ìpìlẹ̀ lábẹ́ gírámà onídàrọ olófin ìyídà náà ni:

- Pípa wúnrẹ̀n (b.a ọ̀rọ̀ arọ́pò afarajorúkọ ẹnìkejì) jẹ nínú gbólóhùn
- Pípàárọ̀ wúnrẹ̀n (b.a ọ̀rọ̀ orúkọ sí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ alátapadà) nínú ihun gbólóhùn
- Ṣíṣe ìfibọ̀ wúnrẹ̀n (b.a àfibọ̀ atọ́ka ìyísódì) sínú ìhun gbólóhùn.
- Ṣíṣe ìgbéfò wúnrẹ̀n láti ipò kan sí òmíràn láti bá òfin àbùdá kan mu nínú ìhun gbólóhùn. (Èyí sábà máa ń wáyé nínú ìṣẹ̀dá gbólóhùn bi; àkíyèsí alátẹnumọ́, gbólóhùn alápèjúwe àti gbólóhùn ìbéèrè).

Ète ìyídà tí ó kàn wá gbọ̀ngbọ̀n nínú iṣẹ́ yìí ni bí a ṣe ń ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún fọ́nrán ìhun gbólóhùn nínú ẹ̀ka-èdè Ọwọ̀. Àkíyèsí alátẹnumọ́ jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀na tí à ń gbà ṣe ìyídà fún gbólóhùn ìpìlẹ̀ láti pe àkíyèsí sí fọ́nrán kan pàtó. Matthews (2007) rí àkíyèsí alátẹnumọ́ gẹ́gẹ́ bi; "an element or part of a sentence given prominence by intonational or other means." Sí Culicover (1976:279) "'this transformation moves constituents to sentence-initial position'." Bákan náà, ní èrò ti Stockwell (1977:137), "'the focus is a way of introducing special marking into the structure of the element that is being focused'." Ouhalla (1994:53) náà jẹ́ kí ó yé wa pé;

> 'Move XP (i.e variables which stand for any phrasal category) and attach it as the leftmost constituent of S.'
>
> (Gbé XP (èyí túmọ̀ sí àpólà kí àpólà) kí o sì so ó mọ́ apá òsì gbólóhùn)

Àmọ́, a ní láti mọ̀ pé àwọn èdè kan bi; Hebrew, Arabic, ati Polish kìí gbé wúnrẹ̀n tí wọ́n bá ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún lọ sí apá òsì gbólóhùn bí kò ṣe apá ọ̀tún rẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé ààyè tí à ó gbé wúnrẹ̀n tí a pe àkíyèsí sí wà lọ́wọ́ èdè tí à ń lò.

Òye àwọn onímọ̀ gírámà tí wọ́n jẹ́ ọmọ Yorùbá náà kò yàtọ̀ sí àwọn tòkè yìí lórí ìṣàkíyèsí alátẹnumọ́. Awobuluyi (1982) jẹ́ kó yé wa pé:

> The word order in any expression containing the particle *ni* is always emphatic. Sentence with topic qualifiers is said to be emphatic in meaning because the particle words in them have been differentiated from or contrasted with all other comparable words of the same part of speech.

Yusuf (1988:57) náà fi yé wa pé: "'Focus is a kind of emphasis that is syntactical-

ly marked through a movement transformation in standard Yorùbá and many other Nigerian languages'."

Ni ti Taiwo (2006),

> Èyí ni gbólóhùn tí a máa ń lò fún pípe àkíyèsí sí yálà fọ́nrán-ìhun gbólóhùn tàbí odidi gbólóhùn. Atọ́ka gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ tí a máa ń lò láti pe àkíyèsí sí fọ́nrán-ìhun ni *ni*. (Taiwo 2006:171)

Ohun tí a rí dìmú ni pé ìṣàkíyèsí alátẹnumọ́ jẹ́ ọ̀kan lára àbùdá èdè káàrí ayé níbi tí elédè ti pe àkíyèsí sí fọ́nrán kan tí ó jẹ ẹ́ lọ́kàn jù nínú ìhun gbólóhùn. Ọ̀nà tí à ń gbà ṣe ìyídà yìí sì wà lọ́wọ́ èdè tí ó bá jẹ́.

## Tíọ́rì Àmúlò

Oríṣìíríṣìí tíọ́rì ni ó wà fún àtúpalẹ̀ gbólóhùn ní abẹ́ gírámà onídàrọ olófin ìyídà bi Tíọ́rì Awòté-wo-gàba àti Tíọ́rì Oníwọ̀nba Èròjà. Tíọ́rì oníwọ̀nba èròjà ni a fi ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí. Tíọ́rì yìí jẹ́ èyí tí Noam Chomsky jẹ́ agbátẹrù rẹ̀ tí ó sì ti ń gbé akitiyan jáde lórí rẹ̀ láti nǹkan bi ọdún (1993). Àfojúsùn tíọ́rì yìí ni láti sọ ìgbésẹ̀ ìṣàtúpalẹ̀ ìhun di péréte ju ti àwọn tíọ́rì ìṣáájú lọ (Chomsky 1995, Marantz 1995, Collins 2011, 2016 etc.). Èròjà pàtàkì tí tíọ́rì yìí ń ṣàmúlò fún ìṣẹ̀dá gbólóhùn ni ìhunpọ̀ (merge). Ìhunpọ̀ ni kí a so ẹyọ-ọ̀rọ̀ tàbí fọ́nrán kan mọ́ òmíràn láti fún wa ní ìhun tí ó tóbi ju ti ìṣáájú lọ. Ìhunpọ̀ oríṣìí méjì ni ó wà ní abẹ́ tíọ́rì yìí; ìhunpọ̀ àtìta àti ìhunpọ̀ abẹ́lé. Ìhunpọ̀ àtìta ni kí a yan ẹyọ-ọ̀rọ̀ tí ó lè bá ara wọn rìn láti inú àká-ọ̀rọ̀ láti ṣẹ̀dá fọ́nrán ìhun kan. Bákan náà, ìhunpọ̀ abẹ́lé ni kí a ṣe ìgbéfò fún ẹyọ-ọ̀rọ̀/fọ́nrán kan tí a ti ṣáájú hun pọ̀ nínú gbólóhùn lọ sí ààyè àsọdọ̀tọ̀ láti gba àbùdá tí ó yẹ nínú gbólóhùn ìyídà tí a ṣẹ̀dá. Ìlànà ìhun àsopọ̀ abèjì ni tíọ́rì yìí fi ń ṣàtúpalẹ̀ ìhun gbólóhùn. Èyí ni pé kò fààyè gba àsopọ̀ fọ́nrán méta tàbí ju bẹ́ẹ̀ lọ ní ìgbésẹ̀ ìsopọ̀ kan ṣoṣo. Àwòrán tí ó wà ní (1) ṣe àfihàn oríṣìí ìhunpọ̀ méjèèjì.

1. (a) Ìhunpọ̀ àtìta (b) Ìhunpọ̀ abẹ́lé




Ìgbéfò kìí déédé wáyé nínú gbólóhùn ìṣẹ̀dá. Ìfàmọ́ra ni ó máa ń fà á. Wúnrẹ̀n tí a bá fà mọ́ra sì gbọdọ̀ ní àbùdá ìṣàyẹ̀wò ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ààyè tí ó fà á mọ́ra. Èyí ni ó mú Chomsky (1995:297) sọ pé

K attracts F if F is the closest feature that can enter into a checking relation with a sublabel of K.

Ohun tí àyọlò òkè yìí ń sọ ni pé, ìfàmọ́ra gbọdọ̀ wáyé kí wúnrẹ̀n kan tó fi ààyè rẹ̀ ìṣáájú sílẹ̀ lọ sí ààyè mìíràn. Wúnrẹ̀n tí ó fi ààyè kan sílẹ̀ lọ sí òmíràn yìí gbọdọ̀ jẹ́ látàrí ìfàmọ́ra tí ó bèèrè fún ìṣíníṗò rẹ̀ nítorí àbùdá ìṣàyẹ̀wò ìbáṣepọ̀ tí ó ní pẹ̀lú ààyè tí ó fà á mọ́ra nínú gbólóhùn.

Tíọ́rì yìí kìí fẹ́ kí á ṣe ìgbéfò àmọ́, tí ó bá pọndandan láti gbé ọ̀rọ̀ fò kí a lè ní gbólóhùn ìyídà tí ó bétí ṣọgba tí ó sì jẹ́ aṣeégbà nínú èdè kan, a ní láti fi àwọn kókó kan sọ́kàn bi; ìlọ́ra, ojútùú-tí-ó-kẹ́yìn, ìgbéfò-ránpẹ́, akitiyan-tí-ó-rọrùn àti ìmọ̀-tara-ẹni-nìkan. A ní láti kọ́kọ́ wa ọ̀nà mìíràn láti ṣẹ̀dá ìyídà tí a fẹ́ ṣe yàtọ̀ sí kí a gbé fọ́nrán. Àsìkò tí à ń ṣe èyí lọ́wọ́ ni ìlọ́ra wáyé. Gbígbé fọ́nrán náà gbọdọ̀ jẹ́ ojútùú tí ó kẹ́yìn lẹ́yìn tí a ti wá ọ̀nà àbáyọ mìíràn fún ìṣẹ̀dá gbólóhùn ìyídà tí a fẹ́ ṣe tí a kò rí. Èyí ni pé, bí a kò bá gbé e, ìyídà àṣeégbà tí a fẹ́ kí ó wáyé, kò ní ṣe é ṣe. Síwájú si, fọ́nrán tí a gbé gbọdọ̀ balẹ̀ sí ààyè tí ó sún mọ́ ọn jùlọ tí wọn jọ ní àbùdá kan náà. Kódà, bí ó bá jẹ́ pé ibẹ̀ kọ́ ni ààyè rẹ̀ ìkẹyìn, ó ní láti kọ́kọ́ balẹ̀ sí ibẹ̀ kí ìgbéfò mìíràn tó gbé e lọ sí ààyè rẹ̀ ìkẹyìn. Ìmọ̀-tara-ẹni-nìkan ní abẹ́ tíọ́rì yìí túmọ̀ sí pè, a gbé ìró kan fún ànfààní ara rẹ̀, láti gba àbùdá tí ó tọ́ sí i ní ààyè tí a gbé e lọ kí ìyídà tí a ṣe lè jẹ́ aṣeégbà.

## Ìṣàkíyèsí Alátẹnumọ́ nínú Èdè Yorùbá

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ ló ti wà lórí ìṣàkíyèsí alátẹnumọ́ lédè Yorùbá bi Awobuluyi (2013; 2001, 1987), Owolabi (1987), Yusuf (1990) abbl. Bí a bá fẹ́ ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún wúnrẹ̀n kan nínú gbólóhùn èdè Yorùbá àjùmọ̀lò, ìgbéfò àti ìlò atọ́ka ìṣàkíyèsí alátẹnumọ́ (AKT) ṣe pàtàkì. Ẹ̀rún "ni" ni à ń lò fún atọ́ka yìí. Bí ìyídà yìí bá fẹ́ wáyé ní abẹ́ tíọ́rì oníwọ̀nba èròjà, a ó so atọ́ka ìṣàkíyèsí alátẹnumọ́ (AKT) mọ́ ìhun gbólóhùn ìpìlẹ̀ lápá òsì nípasẹ̀ ìfibọ̀, a ó sì ṣe ìgbéfò fún fọ́nrán tí a fẹ́ ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún lọ sí apá òsì atọ́ka (AKT) yìí tíí ṣe ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn náà. Èyí túmọ̀ sí pé, atọ́ka AKT wà ní ìfẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú fọ́nrán tí a ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún nínú Yorùbá àjùmọ̀lò. Àpẹẹrẹ 2 jẹ́ ìhun ìpìlẹ̀ nígbà tí (3a-3e) sì jẹ́ gbólóhùn AKT.

| | | |
|---|---|---|
| 2. | Òjó ta bàtà ní Èkó. | (Ìhun ìpìlẹ̀) |
| 3.(a) | Òjó ni ó ta bàtà ní Èkó. | (àkíyèsí alátẹnumọ́ fún olùwà) |
| (b) | Bàtà ni Òjó tà ní Èkó. | (àkíyèsí alátẹnumọ́ fún àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe) |
| (d) | Èkó ni Òjó ti ta bàtà. | (àkíyèsí alátẹnumọ́ fún àbọ̀ ọ̀rọ̀-atọ́kun) |
| (e) | Títà ni Òjó ta bàtà ní Èkó. | (àkíyèsí alátẹnumọ́ fún ọ̀rọ̀-ìṣe) abbl. |

A ó ṣe àkíyèsí pé wúnrẹ̀n tí a ṣe AKT fún ni ó ṣáájú nínú àpẹẹrẹ (3a-e) tí atọ́ka

AKT sì tẹ̀le e pẹ́kípẹ́kí. Bákan náà ni ọ̀rọ̀ rí fún fọ́nrán tí a pe àkíyèsí àtẹnumọ́ fún nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀; a ó gbé e lọ sí apá òsì/ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn àmọ́ ipò atọ́ka ìtẹnumọ rẹ̀ yàtọ̀ sí ti Yorùbá àjùmọ̀lò gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ yìí ṣe fi hàn nísàlẹ̀.

## Ète Ìṣàkíyèsí Alátẹnumọ́ ninu Ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀

Bí àkíyèsí alátẹnumọ́ ṣe ń wáyé nínú Yorùbá àjùmọ̀lò nípa gbígbé fọ́nrán ìtẹnumọ́ lọ sí apá òsì ìhun gbólóhùn náà ni ó ń wáyé nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀. Àmọ́, wúnrẹ̀n tí à ń lò fún atọ́ka AKT nínú Ọ̀wọ̀ yàtọ̀ sí **ni** tí à ń lò nínú Yorùbá àjùmọ̀lò. Bákan náà, ààyè tí atọ́ka AKT yìí ti ń jẹyọ nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ yàtọ̀ sí ti Yorùbá àjùmọ̀lò. Àmì ohùn òkè [´] ni a ṣe àkíyèsí pé à ń lò gẹ́gẹ́ bi atọ́ka AKT nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀, ìgbẹ̀yìn gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ ni ó sì ti ń jẹyọ. Èyí ni pé, ó máa ń takété sí fọ́nrán tí a ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún nínú gbólóhùn. Àpẹẹrẹ

| Ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ | Yorùbá Àjùmọ̀lò |
|---|---|
| 4. Bọ̀dé ta achọ Ìbàdàn. | Bọ̀dé ta aṣọ ní Ìbàdàn (Ìhun ìpìlẹ̀) |
| 5. (a) [Bọ̀dé] ó ta achọ Ìbàdàn án. | [Bọ̀dé] ni ó ta aṣọ ní Ìbàdàn. (AKT fún olùwà) |
| (b) [Achọ] Bọ̀dé tà Ìbàdàn án. | [Aṣọ] ni Bọ̀dé tà ní Ìbàdàn.(AKT fún àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe) |
| (d) [Ìbàdàn] Bọ̀dé ti ta àchọ̀ ọ́. | [Ìbàdàn] ni Bọ̀dé ti ta aṣọ. (AKT fún àbọ̀ ọ̀rọ̀-atọ́kun) |
| (e) [Títà] Bọ̀dé ta achọ Ìbàdàn án. | [Títà] ni Bọ̀dé ta aṣọ ní Ìbàdàn. (AKT fún ọ̀rọ̀-ìṣe) |
| (ẹ) [Fi Bọ̀dé ta achọ nẹ́ẹ̀ Ìbàdàn] mò fọ̀ ọ́. | [Pé Bọ̀dé ta aṣọ náà ní Ìbàdàn] ni mo sọ. (AKT fún àpólà amúpé) |

Lẹ́yìn tí a gbé fọ́nrán tí a fẹ́ ṣe AKT fún lọ sí ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn, a ṣe àkíyèsí pé wúnrẹ̀n kan jẹyọ tí ó ní àmì ìró ohùn òkè lórí ní ìgbẹ̀yìn gbólóhùn AKT kọ̀ọ̀kan nínú àpẹẹrẹ (5a-ẹ). Wúnrẹ̀n yìí wà lọ́wọ́ sílébù tí ó gbẹ̀yìn gbólóhùn kọ̀ọ̀kan àmọ́ àmì ohùn orí wọn kò yàtọ̀. Èyí fi yé wa pé níwọ̀n ìgbà tí àmì ohùn kò lè dá dúró àfi kí ó dúró sórí sílébù, ìdí nìyí tí ó fi yan sílébù tí ó kẹ́yìn ìhun gbólóhùn AKT láàyò láti dúró lè. Èyí ni ó jẹ́ kí a rí wúnrẹ̀n bi **an** àti **ọ** ní ipò atọ́ka láti gbé àmì ohùn òkè tí ẹ̀ka-èdè náà ń ṣà múlò rù nínú àpẹẹrẹ (5). Bí a bá wòye pé ìfẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ ni ó yẹ kí atọ́ka yìí wà sí fọ́nrán tí a ṣe AKT fún gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú Yorùbá àjùmọ̀lò, àbájáde gbólóhùn bẹ́ẹ̀ nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ yóò yọrí sí ìhun àìṣeégbà bí ó ti hàn ní 6.

| | |
|---|---|
| 6. (a) *[Bọ̀dé] **é** ó ta achọ Ìbàdàn. | [Bọ̀dé] **ni** ó ta aṣọ ní Ìbàdàn. (AKT fún olùwà) |

(b) *[Achọ] **ọ́** Bọ̀dé tà Ìbàdàn. [Aṣọ] **ni** Bọ̀dé tà ní Ìbàdàn.(AKT fún àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe)


(d) *[Ìbàdàn] **án** Bọ̀dé ti ta àchọ̀. [Ìbàdàn] **ni** Bọ̀dé ti ta aṣọ. (AKT fún àbọ̀ ọ̀rọ̀-atọ́kun)

## Àtúpalẹ̀ Gbólóhùn AKT nínú Ẹ̀ka-Èdè Ọ̀wọ̀

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú tí a sì tún rí i nínú àwọn àpẹẹrẹ tí ó wà lókè, kò sí fọ́nrán ìhun tí a kò lè ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún nínú gbólóhùn. Òhun tí ó kàn láti ṣe ni kí á wo bí ìgbésẹ̀ ìyídà ṣe ń wáyé nígbà tí a bá ṣe ìyídà yìí fún fọ́nrán ìhun kọ̀ọ̀kan nínú gbólóhùn lábẹ́ tíọ́rì oníwọ̀nba èròjà.

### Ìṣàkíyèsí Alátẹnumọ́ fún Olùwà Gbólóhùn

7. (a) Bọ̀dé ta achọ Ìbàdàn. Bọ̀dé ó ta achọ Ìbàdàn **án**.




Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn ní (7b), láti ṣe AKT fún olùwà gbólóhùn, a hun ìró ohùn òkè [´] tíí ṣe atọ́ka AKT mọ́ gbólóhùn ìpìlẹ̀ ní apá òsì. Atọ́ka AKT yìí ṣe ìfàmọ́ra fún fọ́nrán tí a fẹ́ pe àkíyèsí àtẹnumọ fún (olùwà) a sì ṣe ìgbéfò nípasẹ̀ ìhunpọ̀ abẹ́lé fún ọ̀rọ̀ orúkọ tí ó wà ní ipò olùwà yìí lọ sí ààyè àsọdọ̀tọ̀ tí ó wà ní apá òsì APKT láti lọ gba àbùdá AKT kí ìdàrọ náà tó lè di ṣíṣe. Ààyè tí OR yìí wà tẹ́lẹ̀ kò ní ṣófo, ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ adelé yóò wà níbẹ̀. Ìdí nìyí tí a fi rí ***ó*** ní ààyè yìí. Ìgbéfò tí ó wáyé yìí ṣe pàtàkì ní ìbámu pẹ̀lú nǹkan tí àbùdá AKT sọ gẹ́gẹ́ bí a ti ri nínú Brody (1990) tí ó wí pé;

> At the appropriate level of representation, every +F-Phrase must be in a spec-head relation with a head endowed with the feature [+F].


Kí ìyídà yìí tó lè jẹ́ aṣeégbà nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀, ìró ohùn òkè tó jẹ́ atọ́ka AKT yìí ní láti takété sí fọ́nrán tí a ṣe àkíyèsí àtẹnumọ́ fún, nípa jíjẹyọ ní ìgbẹ̀yìn gbólóhùn

tí a ṣẹ̀dá náà. Níwọ̀n ìgbà tí ìró ohùn kò lè dá dúró àfi kí ó dúró sórí sílébù, ìdí nìyí tí ó fi yan ìrísí sílébù tí ó kẹ́yìn ìhun gbólóhùn AKT láàyò láti dúró lé gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn ní (7d) lókè.

## Iṣàkíyèsí Alátẹnumọ́ fún Àbọ̀ Ọ̀rọ̀-Ìṣe

8. (a) Bọ̀dé ta achọ Ìbàdàn. → [Achọ] Bọ̀dé tà <achọ> Ìbàdàn **án**.

(b)





A ṣe àkíyèsí pé lẹ́yìn tí ìgbéfò wáyé fún àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe láti ipò tí ó wà tẹ́lẹ̀ lọ sí ipò àsọdọ̀tọ̀ APKT, àkámọ́ onígun "< >'rọ̀gbà yí èyí tó wà níbẹ̀ tẹ́lẹ̀ ká. Àkámọ́ yìí ni ó jẹ́ kí á mọ̀ pé a ti gbé ọ̀rọ̀ náà, a kò sì ní pè é. Èyí yàtọ̀ sí bí a ṣe ń fi ìgbéfò hàn pẹ̀lú àmì "$t_i$" nínú tíọ́rì ìṣáájú (tíọ́rì awòtéwogàba). Lẹ́yìn èyí ni ìyídà yí ààyè atọ́ka AKT láti ẹ̀gbẹ́ fọ́nrán tí a tẹnumọ́ lọ sí ìgbẹ̀yìn gbólóhùn tí a dàrọ náà gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn ní (8).

## Ìṣàkíyèsí Alátẹnumọ́ fún Àbọ̀ Ọ̀rọ̀-Atọ́kun

9. (a) Bọ̀dé ta achọ Ìbàdàn. → [Ìbàdàn] Bọ̀dé ti ta àchọ̀ <Ibadan> **ọ́**.

(b)



Ọ̀rọ̀ atọ́kùn *ni* kò fojú hàn nínú ìhun gbólóhùn òkè yìí, ìdí nìyí tí a fi rí kòròfo mọ́fíìmù níbi tí ó yẹ kí ó wà. Bí a bá ṣe AKT fún àbọ̀ ọ̀rọ̀ atọ́kùn yìí, akópa tí ó wà ní ipò àbọ̀ náà yóò gbéra nípasẹ̀ ìgbéfò lọ sí ipò àsọdọ̀tọ̀ láti gba àbùdá AKT. Atọ́ka AKT yóò sì jẹyọ ní ìgbẹ̀yìn gbólóhùn tí a dàrọ náà látàrí ipa òfin ìyídà bí ó ti hàn ní (9) lókè. A ṣe àkíyèsí wí pé àmì ohùn orí *achọ* (re...re) inú ìhun ìpìlẹ̀ paradà di *dò...dò* nínú ìhun òkè tí a dàrọ. Ìdí ni pé ẹ̀wọ́n tí àmì ohùn ìsàlẹ̀ parí rẹ̀ ni ó gbọdọ̀ wà ṣáájú ìró ohùn òkè tó ń ṣiṣẹ́ atọ́ka àkíyèsí àtẹnumọ nínú ẹ̀ka-èdè Ọwọ̀.


## Ìṣàkíyèsí Alátẹnumọ́ fún Ọ̀rọ̀-Ìṣe

Láti ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún ọ̀rọ̀-ìṣe gbólóhùn, a ní láti kọ́kọ́ ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ orúkọ láti ara rẹ̀ nípasẹ̀ àpètúnpè ẹlẹ́bẹ. Ìdí ni pé, wúnrẹ̀n tí ó ní àbùdá ìjẹmórúkọ ni ó máa ń wà ní ipò àsọdọ̀tọ̀ APKT. Ojúlówó ọ̀rọ̀-ìṣe inú ìhun ìpìlẹ̀ yóò wà ní ààyè rẹ̀, nígbà tí ìgbéfò yóò gbé èyí tí a ṣẹ̀dá lọ sí ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn láti gba àbùdá AKT. Bí bẹ̀ẹ̀ kọ́, gbólóhùn tí kò ṣeégbà fún ìdàrọ AKT ni àbájáde ìyídà náà yóò fún wa, bí ó ti hàn ní (10a). (10b) sì jẹ́ aṣeégbà èyí tí a fi àtẹ onígi rẹ̀ hàn ní (10d).

10. (a) Bọ̀dé ta achọ Ìbàdàn. *Tà Bọ̀dé ta achọ Ìbàdàn **án**.

(b) Títà Bọ̀dé ta achọ Ìbàdàn **án**.

(d)





## Ìṣàkíyèsí Alátẹnumọ́ fún Àpólà Amúpé

Yàtọ̀ sí àwọn fọ́nrán ìhun gbólóhùn abọ́dé tí a ṣe àfìhan lókè, a tún lè ṣe AKT fún àpólà amúpè nínú gbólóhùn oníbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn ní (11).

11. (a) Mo fọ̀ fi Bọ̀dé ta achọ nẹ́ẹ̀ Ìbàdàn. (b) [Fi Bọ̀dé ta achọ nẹ́ẹ̀ Ìbàdàn] mo fọ̀ ọ́.

(d)





Láti ṣe àkíyèsí àtẹnumọ́ fún àpólà amúpé (*fi Bọ̀dé ta achọ nẹ́ẹ̀ Ìbàdàn*) inú gbólóhùn oníbọ̀ tí ó wà ní (11a), a gbé àpólà amúpé náà lọ sí àáyè àsọdọ̀tọ̀ tí ó wà ní apá òsì látàrí ìfàmọ́ra tí atọ́ka AKT náà ṣe sí i láti lè lọ gba àbùdá àkíyèsí alátẹnumọ́. Lẹ́yìn èyí ni ìyídà yí àáyè atọ́ka AKT láti ẹ̀gbẹ́ fọ́nrán tí a tẹnumọ́ lọ sí ìgbẹ̀yìn gbólóhùn tí a dàrọ náà gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn ní (11d) lókè.

Ohun tí a ṣe àkíyèsí ni pé, láti ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún fọ́nrán kankan nínú gbólóhùn ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀, a ó hun atọ́ka AKT (ìró ohùn òkè) mọ́ ìhun ìpìlẹ̀ (APAR) lápá òsì nípasẹ̀ ìhunpọ̀ àtìta. Èyí yòó jẹ́ kí àtẹ onígi wa ṣí sí APKT (tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àkóónú APAM). Fọ́nrán tí a bá fẹ́ ṣe AKT fún yóò di gbígbéfò nípasẹ̀ ìhunpọ̀ abẹ́lé láti àáyè tí ó wà tẹ́lẹ̀ lọ sí ipò àsọdọ̀tọ̀ APKT látàrí ìfàmọ́ra tí atọ́ka AKT fi bèèrè fún ìṣínípò rẹ̀. Lẹ́yìn èyí ni ìyídà yóò yí àáyè atọ́ka AKT láti ẹ̀gbẹ́ fọ́nrán tí a tẹnumọ́ lọ sí ìgbẹ̀yìn gbólóhùn tí a dàrọ náà. Ìrísí sílébù tí ó bá gbẹ̀yìn ìhun tí a dàrọ yìí sì ni ìró ohùn òkè tí ó jẹ́ atọ́ka AKT náà máa ń yàn láàyò láti dúró lé nítorí ègé ìró alágbèéká tí ó jẹ́. Èyí fi hàn pé atọ́ka AKT ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ á máa takété sí fọ́nrán tí a ṣe AKT fún. Ohun tí a wí ní ààrín yìí ni a fi àtẹ-onígi ṣe àlàyé rẹ̀ sísàlẹ̀ ní (12):

Ìhun gbólóhùn AKT fún ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀:

12(a) (b)




Kí a tó yí àáyè atọ́ka AKT

Lẹ́yìn tí a yí àáyè atọ́ka AKT

### Ẹ̀rí fún Àmì Ohùn Òkè gẹ́gẹ́ bi Atọ́ka Àkíyèsí Alátẹnumọ́ nínú Ẹ̀ka-Èdè Ọ̀wọ̀

A kò déédé sọ pé ìró ohùn òkè ni atọ́ka àkíyèsí alátẹnumọ́ nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ bí kò ṣe nípa àwọn kókó tí ó dúró bíi ẹ̀rí-máa-jẹ́-mi-nìṣọ̀ó tí a mẹ́nubà nísàlẹ̀ yìí.

### Ìbáṣepọ̀ Gbólóhùn Àkíyèsí Alátẹnumọ́ àti Gbólóhùn Ìbéèrè

Ìbáṣepọ̀ tí ó yanranntí wà láàárín gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ àti gbólóhùn ìbéèrè nítorí pé gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ máa ń jẹ́ ìdáhùn sí gbólóhùn ìbéèrè. Ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín irúfẹ́ gbólóhùn méjèèjì yìí ni ó ṣe okùnfà atọ́ka **ni** tí ó ń jẹyọ nínú wọn bí ó ti hàn nínú Yorùbá àjùmọ̀lò àti àwọn ẹ̀ka-èdè rẹ̀ kan. Iṣẹ́ àkíyèsí alátẹnumọ́ ni a gbàgbọ́ pé **ni** yìí ń ṣe, ààyè kan náà sì ni ó ti ń jẹyọ nínú oríṣìí gbólóhùn méjèèjì. Bí àpẹẹrẹ:

| Gbólóhùn Ìbéèrè | Gbólóhùn Àkíyèsí Alátẹnumọ́ |
|---|---|
| 13. (a) Ta ni ó ta aṣọ ní Ìbàdàn? | (b) Bọ̀dé ni ó ta aṣọ ní Ìbàdàn. |
| 14. (a) Kí ni Bọ̀dé tà ní Ìbàdàn? | (b) Aṣọ ni Bọ̀dé tà ní Ìbàdàn. |
| 15. (a) Ibo ni Bọ̀dé ti ta aṣọ? | (b) Ìbàdàn ni Bọ̀dé ti ta aṣọ. |

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé atọ́ka àkíyèsí àtẹnumọ́ inú gbólóhùn ìbéèr̀e inú àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá kan yàtọ̀ sí èyí tí wọ́n ń lò nínú gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́, síbẹ̀ ọ̀gangan kannáà ni àwọn atọ́ka yìí ti ń jẹyọ nínú oríṣìí gbólóhùn méjèèjì bí ó ti hàn nínú ẹ̀ka-èdè Ẹ̀gbá tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí (16-17).

| Gbólóhùn Ìbéèrè | Gbólóhùn Àkíyèsí Alátẹnumọ́ |
|---|---|
| 16. (a) Ìyí sí o fẹ́ràn? | (b) Ìyí re mo fẹ́ràn. |
| 17. (a) Líbi sí owó wà nọ? | (b) Ọjà re owó wà. (Omolewu, 2014) |

Ó hàn gbangba pé **sí** ló ń ṣe iṣẹ́ atọ́ka AKT nínú gbólóhùn ìbéèrè ẹ̀ka-èdè Ẹ̀gbá, nígbà tí **re** sì ń ṣe iṣẹ́ kannáà nínú gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́. Àmọ́, ipò tàbí ààyè kannáà ni wọ́n ti ń jẹyọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn lókè.

A ṣé àkíyèsí pé, ààyè kan náà ni àmì ohùn òkè tí a kà sí atọ́ka AKT nínú ẹ̀ka-èdè Ọ̀wọ̀ ti ń jẹyọ nínú gbólóhùn ìbéèrè àti gbólóhùn àkĩyèsí alátẹnumọ́. Ẹ̀rí máa-jẹ́-mi-nìṣọ̀ó nípa àkíyèsí yìí ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

| Gbólóhùn Ìbéèrè | Gbólóhùn Àkíyèsí Alátẹnumọ́ |
|---|---|
| 18. (a) Sùé ta achọ Ìbàdàn án? | (b) Bọ̀dé ó ta achọ Ìbàdàn án. |
| 19. (a) Kí ni Bọ̀dé tà Ìbàdàn án? | (b) Achọ Bọ̀dé tà Ìbàdàn án. |

20. (a) Kẹ̀ẹ́ ibi Bọ̀dé ti ta àchọ̀ ọ́? (b) Ìbàdàn Bọ̀dé ti ta àchọ̀ ọ́.

## Ìjẹyọ Atọ́ka Àkíyèsí Alátẹnumọ́ ní Ìgbẹ̀yìn Gbólóhùn AKT nínú Èdè mìíràn.

Ìdí mìíràn tí a fi gbà wí pé àmì ohùn òkè ni ó ń ṣiṣẹ́ atọ́ka AKT nínú ẹ̀ka-èdè Ọwọ̀ ni pé, a rí àwọn èdè mìíràn tí ó jẹ́ pé bákan lọmọ ṣorí lọ́dọ̀ wọn. Èdè Ọwọ̀ nìkan kọ́ ni atọ́ka àkíyèsí alátẹnumọ́ rẹ̀ máa ń jẹyọ ní ìgbẹ̀yìn gbólóhùn. A rí àwọn èdè mìíràn (bi Òkèàgbè, Oǹdó, Ìkálẹ̀ abbl.) tí atọ́ka àkíyèsí alátẹnumọ́ wọn máa ń wà ní òpin gbólóhùn AKT. Bí àpẹẹrẹ

21. (a) Òkèàgbè: Ìwé mu dà **á**.

(b) Oǹdó: Ìwé mo à **ín.**

(d) Ìkálẹ̀: Ìwé mo rà **rín**.

(e)Yorùbá àjùmọ̀lò: Ìwé **ni** mo rà. (Awobuluyi 2001:13)

## Ìgúnlẹ̀

Bébà yìí ṣe àfihàn ète tí a fi ń ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ nínú ẹ̀ka-èdè Ọwọ̀. Ó fi hàn pé ìró ohùn òkè ni à ń lò fún atọ́ka àkíyèsí alátẹnumọ́ nínú ẹ̀ka-èdè yìí, ìgbẹ̀yìn gbólóhùn sì ni ó ti ń jẹyọ lẹ́yìn tí a bá ti ṣe ìgbéfò abẹ́lé fún fọ́nrán tí a fẹ́ ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún lọ sí ààyè àsọdọ̀tọ̀ ní ápá òsì gbólóhùn. Ó sì tún jẹ́ kí ó yé wa ní ìbámu pẹ̀lú Yorùbá àjùmọ̀lò pé, kò sí fọ́nrán ìhun gbólóhùn tí a kò lè ṣe àkíyèsí alátẹnumọ́ fún nínú ìhun gbólóhùn ẹ̀ka-èdè Ọwọ̀.

## ÀKÓJỌPỌ̀ ORÚKỌ ÌWÉ


Awobuluyi, O. (1982). The Yorùbá verb phrase. Nínu A. Afolayan (Ed.) *Yorùbá Language and Literature* (225-246). Ife: University Press.

Awobuluyi, O. (1987). Focus constructions as noun phrases: A reply. *Yoruba New Series* (1), 73-87.

Awobuluyi, O. (2001). Ìtàn èdè Yorùbá. Nínu B. Ajayi (Ed.) *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹdá-èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà* (pp. 8-28). Ijebu-Ode: Shebiotimo Publications.

Awobuluyi, O. (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* Osogbo: Atman Ltd.

Brody, M. (1995). "Focus and checking theory." In Kenesei (Ed.) *Approaches to Hungarian* (5) JATE, Szeged.

Chomsky, N. (1986). *Barriers*. London: The MIT Press.

Chomsky, N. (1993). A minimalist program for linguistic theory. In Hale and Keyser (Eds.) *View from building 20: Essays in Linguistics in Honour of Sylvain Bromberger* (pp. 1-52). Cambridge: MIT Press

Chomsky, N. (1995). *The Minimalist Program*. Cambridge Mass: The MIT Press.

Collins, C. (2011). *Introduction to Minimalist Syntax*. New York: New York University Press.

Collins, C. (2016). Introduction to minimalist syntax: The African Linguistics School Lectures. A Paper Presented at the African Linguistic School 4, Abidjan.

Culicover, P.W. (1976). *Syntax and Semantics*. Volume 4. New York: Academic Press.

Eleshin, A.F. (2019). Clause structure analysis of Olùkùmi and Ọ̀wọ̀: Two related but non-contiguos Yorùbá dialects. Phd. dissertation, University of Lagos.

Lamidi, M.T. (2008). *Aspects of Chomskyan Grammar*. Ibadan: University Press Plc.

Marantz, A. (1995). "The minimalist program." In W. Gert (Ed.) *Government and Binding and the Minimalist Program*. Oxford: Blackwell Publishers.

Matthews, P.H. (2007). *Oxford Concise Dictionary of Linguistics* (*2nd Edition*). Oxford: Oxford University Press.

Omolewu, O. (2014). "Focus construction and negation of focused constituents in Ẹ̀gbá dialect" in A.S. Abdulssalam, L. Adeyemi, H. O. Adeosun, & B. Arokoyo (Eds.), *Bringing our Cultures Home: Festschrift for Bade Ajayi at 70* (pp. 312-334). Ilorin: Chridamel Publishing House.

Ouhalla, J. (1994). *Introducing Transformational Grammar*: *From Rules to Principles and Parameters*. London: Edward Arnold.

Owolabi, D.K.O. (1987). Focus construction as noun phrase: A Critique. Nínu *YORÙBÁ: Journal of Yoruba Studies Association of Nigeria* (*New Series*). (1) 45-62.

Radford, A. (1988). *Transformational Grammar*. Cambridge: Cambridge University Press.

Stockwell, R. (1977). *Foundation of Syntactic Theories*. New Jersey: Prentice Hall Inc.

Taiwo, O. (2006). *Mofọ́lọ́jì*. Ibadan: Layof Ventures Publishing Educational Services.

Yusuf, O. (1988). The derivation of focus construction in Yoruba: A problem for the trace theory. *Journal of the Linguistics Association of Nigeria* (*JOLAN*) (5) 56-72.

Yusuf, O. (1990). Yoruba copula *ni.* Nínu *Journal of West African Languages* (20) 83-93.

## Ìtọsẹ̀ ọ̀rọ̀

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a gé kúrú

| | | | |
|---|---|---|---|
| APAM | Àpólà Amúpé | ASD | Àsọdọ̀tọ̀ |
| APKT | Àpólà Àkíyèsí Alátẹnumọ́ | APIṢ | Àpólà Ọ̀rọ̀-Ìṣe |
| AKT' | Àkíyèsí Alátẹnumọ́ Onípele | IṢ | Ọ̀rọ̀-Ìṣe |
| AKT | Atọ́ka Àkíyèsí Alátẹnumọ́ | APOR | Àpólà Ọ̀rọ̀-Orúkọ |
| APAR | Àpólà Apàrísídà | OR | Ọ̀rọ̀-Orúkọ |
| AR' | Apàrísídà Onípele | APAT | Àpólà Ọ̀rọ̀-Atọ́kùn |
| AR | Apàrísídà | OAT | Ọ̀rọ̀-Atọ́kùn |